## (99) Suratul - Salsalah

سُورَةُ الزَّلْزَلَةِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Nigbati ilẹ̀ ba mi titi ni mimi rẹ̀.

إِذَا زُلْزِلَتِ ٱلْأَرْضُ زِلْزَالَهَا ﴿١﴾

**2.** Ti ilẹ̀ yio tu ẹrù wuwo inu rẹ̀ jade.

وَأَخْرَجَتِ ٱلْأَرْضُ أَثْقَالَهَا ﴿٢﴾

**3.** Enia yio sọpe: kiniṣe e?

وَقَالَ ٱلْإِنسَٰنُ مَا لَهَا ﴿٣﴾

**4.** Ọjọ na ni (ilẹ̀) yio sọ irohin rẹ̀.

يَوْمَئِذٍ تُحَدِّثُ أَخْبَارَهَا ﴿٤﴾

**5.** Nitoripe Oluwa rẹ ti ranṣẹ si i.

بِأَنَّ رَبَّكَ أَوْحَىٰ لَهَا ﴿٥﴾

**6.** Ọjọ na awọn enia yio gba ọna ọ̀tọ̃tọ̀, ki a le fi iṣẹ wọn hàn wọn.

يَوْمَئِذٍ يَصْدُرُ ٱلنَّاسُ أَشْتَاتًا لِّيُرَوْا۟ أَعْمَٰلَهُمْ ﴿٦﴾

**7.** Nitorina ẹniti o ba ṣe iṣẹ rere bi ọmọ-inagun yio ri i.

فَمَن يَعْمَلْ مِثْقَالَ ذَرَّةٍ خَيْرًا يَرَهُۥ ﴿٧﴾

**8.** Atipe ẹniti o ba ṣe iṣẹ buburu bi ọmọ-inagun yio ri i.

وَمَن يَعْمَلْ مِثْقَالَ ذَرَّةٍ شَرًّا يَرَهُۥ ﴿٨﴾

## (100) Suratul - 'Ãdiyãti

سُورَةُ العَادِيَاتِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Mo fi awọn ẹṣin ti nsare (lojuogun) ni mimi hẹlẹhẹlẹ ('Adiyãti) bura.

وَٱلْعَٰدِيَٰتِ ضَبْحًا ﴿١﴾

**2.** Ati awọn ẹṣin ti patako ẹsẹ̀ wọn nṣana.

فَٱلْمُورِيَٰتِ قَدْحًا ﴿٢﴾

**3.** Ati awọn ẹṣin ti nwọ inu ogun ni idaji.

فَٱلْمُغِيرَٰتِ صُبْحًا ﴿٣﴾